# ÀLÀKALẸ̀ AMẸ́RÍKÀ FÚN ÌHÀ GÚÚSÙ SAHARA ILẸ̀ ÁFRÍKÀ

OṢÙ KẸJỌ ỌDÚN 2022

★ ★ ★ ★ ★ ★

**“A gbàgbọ́ nínú àwọn orílẹ̀-èdè ilẹ̀ Áfríkà, nínú ìfọkànsìn fún iṣẹ́ okòòwò àti ọgbọ́n àtinúdá àgbáríjọpọ̀ wọn. Lórí àwọn àdojúkọ tó wà níwájú, bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n lágbára, kò sí iyèméjì pé àwọn orílẹ̀-èdè wa, àwọn èèyàn wa, Àjọ Ìṣọ̀kan Afríkà—a kúnjú òṣùwọ̀n lórí rẹ̀.**

Aarẹ Joe Biden
Ìpàdé Àpérò Àjọ Ìṣọ̀kan Áfríkà
Ọjọ́ Karùn-ún Oṣù Kejì, Ọdún 2021

★ ★ ★ ★ ★ ★

# ATỌ́KA ÀWỌN ÀKÓÓNÚ


I. Ọ̀rọ̀ Ìgbìmọ̀ Aláṣẹ ní Ṣókí
II. Agbègbè tí Àlàkalẹ̀ Yóò ti Wáyé
III. Àfojúsùn Àlàkalẹ̀
Gbígbé Àjọṣepọ̀ àti Àkóyawọ́ Lárugẹ
Ṣíṣàgbékalẹ̀ Àǹfààní Ètò Ìjọba Àwarawa àti Ààbò
Mímú Ìlọsíwájú Bá Ìlànà Bíbọ́ Lọ́wọ́ Àjàkálẹ̀ Àrùn àti Àǹfààní Ètò Ọrọ̀-Ajé
Gbígbárùkù ti Ìdáàbòbò, Ìfarada Ojú-Ọjọ́ àti Ìṣípòpadá sí Nǹkan Àmúṣagbára tó Dáa fún Gbogbo Èèyàn
IV. Àjọṣepọ̀ Ilẹ̀ Amẹ́ríkà àti Áfríkà ní Sẹ́ńtíúrì Kọkànlélógún
V. Ìlànà Tí A Fẹ́ẹ̀ Lò
VI. Ìparí

# ỌRỌ̀ ÌGBÌMỌ̀ ALÁṢẸ NÍ ṢÓKÍ

Ìhà Gúúsù Sahara ilẹ̀ Áfríkà jẹ́ ọ̀kan gbòógì nínú àwọn ètò wa. Ó jẹ́ ọ̀kan nínú ibi tí àwọn èèyàn ti ń pọ̀ sí i jù lágbàáyé, ibi tí òmìnira okòòwò pọ̀ sí jù, ibi tí oríṣìíríṣìí ètò ìbágbepọ̀ ẹ̀da pọ̀ sí jù, àti ọ̀kan nínú agbègbè tí àwọn tó ń dìbò ní Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé (UN) pọ̀ sí jù. Kò ṣeé ṣe láti kojú àwọn ìpèníjà òde-òní láì sí ìdásí tàbí ìdarí Áfríkà níbẹ̀. Agbègbè yìí yóò búyọ nínú ìgbìyànjú láti: fòpin sí àrùn COVID-19; kojú wàhálà ojú-ọjọ́; mú àyípadà bá ìjọba àwarawa tó ń fàsẹ́yìn lágbàáyé; dá sí àìtó oúnjẹ lágbàáyé; ró ìdúróṣinṣin èto àgbáyé lágbára; ṣàtúnrọ òfin àgbááyé lóri àwọn nǹkan pàtàkì bíi okòòwò, ètò àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé, àti ìmọ̀-ẹ̀rọ tuntun; pẹlu gbígbógun ti ìfẹ̀míṣòfò, rògbòdìyàn, àti ìwà ọ̀daràn orílẹ̀-èdè sí orílẹ̀-èdè.

> **“Àlàkalẹ̀ yìí ṣàtúnṣe sí bí agbègbè yìí ṣe ṣe pàtàkì sí ohun tó jẹ ètò ààbò Amẹ́ríkà lógún.**

Àlàkalẹ̀ yìí ṣàtúnṣe sí bí agbègbé yìí ṣe ṣe pàtàkì sí ohun tó jẹ ètò ààbò Amẹ́ríkà lógún. Lóṣù kọkànlá, ọdún 2021, Akọ̀wé Ìjọba Antony Blinken fìdí ẹ̀ múlẹ̀ pé “Áfríkà yóò ṣàtúnrọ ọjọ́-iwájú—bẹ́ẹ̀ ni kì í ṣe ọjọ́ iwájú àwọn èèyàn Áfríkà nìkan ṣùgbọ́n ti àgbáyé.” Ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé, àlàkalẹ̀ yìí ṣàlàyé àfojúsùn lórí ọna àti pẹ̀lú ẹni tí a bá ṣe pọ̀, nígbà tó tún ń ṣèdánimọ̀ àwọn àfojúsùn mí-ìn. Ó fààyè gba àjọ Áfríkà, ó sì fòǹtẹ̀ lù ú, bẹ́ẹ̀ ló lépa láti gbé ohùn Áfríkà sókè nínú ìtàkurọ̀sọ nípa àwọn nǹkan tó ṣe pàtàkì lágbàáyé. Ó pè fún ìgbélárugẹ àwọn alábàáṣepọ̀ tó làmìlaaka àti ìṣètò agbègbè lọ́nà tó fààyè gba àyípadà láti kojú ìpèníjà pàjáwìrì àti láti jẹ́ kí ìdàgbàsókè àtàwọn àǹfààní ọrọ̀-ajé bẹ̀rẹ̀. Ó rí àwọn ọ̀dọ́ agbègbè náà bíi agbára okòòwò àti àtinúdá, bẹ́ẹ̀ ló tẹnu mọ́ ìbaṣepọ̀ àwọn èèyàn Áfríkà àti Amẹ́ríkà tó dúró ṣinṣin láti ọjọ́ pípẹ́. Bẹ́ẹ̀ ló ṣàtúntò àwọn ìlànà àtijọ́ tí Amẹ́ríkà ń lò—ìjọba àwarawa àti ètò ìṣèjọba, àláàfíà àti ètò ààbò, katà-karà àti ìdókòòwò, pẹ̀lú ìdàgbàsókè—gẹ́gẹ́ bíi ọ̀nà láti ṣàtìlẹ́yìn fún agbára agbègbè yii láti wá ojútùú sí ìṣòro àgbáyé pẹ̀lú àjọṣepọ̀ Amẹ́ríkà.

Àlàkalẹ̀ yìí ṣàlàkalẹ̀ àwọn àfojúsùn mẹ́rin láti ṣègbélárugẹ àwọn nńkan tó jẹ Amẹ́ríkà lógún nínú ájọ̀ṣepọ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ ní Ìha Gúúsù Sahara Áfríkà lọ́dún márùn-ún sí àsìkò yìí. Amẹ́ríkà yóó lo àǹfààní gbogbo àjọṣepọ̀, ìdàgbàsókè, àtàwọn agbára ààbò, pẹ̀lú ríró ìbáṣepọ̀ wa nílànà kátà-kárà àti okòòwò lágbára, gbígbájú mọ́ ètò ìbágbepọ̀ nípa àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé, pẹ̀lu mímú àwọn ibùdó ìlú dúró ṣinṣin nílànà ìgbàlódé, láti gbárùkù ti àwọn àfojúsùn wọ̀nyí:

1. **Gbé Àkóyawọ̀ àti Àwujo ti o ni Àkóyawọ̀ Lárugẹ**
2. **Ṣàgbékalẹ̀ Àǹfààní Ètò Ìjọba Àwarawa àti Ààbò.**
3. **Mú Ìlọsíwájú Bá Ìlànà Bíbọ̀ Lọ́wọ̀ Àjàkálẹ̀ Àrùn àti Àǹfààní Ètò Ọrọ̀-Aje Gbárùkù ti Ìdáàbòbò, Ìfarada Ojú-Ọjọ́ àti Ìṣípòpadá sí Nǹkan Àmúṣagbára tó Dáa fún Gbogbo Èèyàn**
4. **Gbárùkù ti Ìdáàbòbò, Ìfarada Ojú-Ọjọ́ àti Ìṣípòpadá sí Nǹkan Àmúṣagbára tó Dáa fún Gbogbo Èèyàn**

Àlàkalẹ̀ yìí tọ́ka sí ọ̀nà tuntun, bẹ́ẹ̀ ló tẹnu mọ́ tó sì ṣe ìgbélárugẹ fún àwọn nǹkan tí yóò ṣàtúnrọ ipò tí Áfríkà yóò wà ní ọjọ́ iwájú gbogbo wa. Ó pinnu láti làkàkà fún àwọn nǹkan àti ẹ̀bùn tó ṣe pàtàkì fún ìgbìyànjú láti fún ìbáṣepọ̀ wa lágbára. Amẹ́ríkà yóó dá sí rògbòdìyàn àti ìdúnkookò tó wà lọ́wọ́lọ́wọ́, bẹ́ẹ̀ ni yóò lépa láti ṣe àsopọ̀ ìgbìyànjú ọlọ́jọ́-díẹ̀ àti ètò ọlọ́jọ́-pípẹ́ tó pọn dandan láti gbárùkù ti agbára Áfríkà láti wá ojútùú sí ìṣòro àgbáyé. Agbára àlàkalẹ̀ náà wà nínú ìpinnu láti yẹra fún áwọn òfin tó ń fojú tẹ́ḿbẹ́lú Ìha Gúúsù Sahara Áfríkà tó sì tiraka láti wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn nǹkan ọ̀tun tó ń ṣẹlẹ̀ lágbègbè náà àti àgbáyé. Àlàkalẹ̀ yìí pè fún àyípadà nítorí ìtẹ̀síwájú kò tó láti kojú àwọn iṣẹ́ tó wà níwájú.

★ ★ ★ ★ ★ ★

# AGBÈGBÈ TÍ ÀLÀKALẸ̀ YÓÒ TI WÁYÉ

Àwọn ìjọba, ẹ̀ka àti èèyàn Ìha Gúúsù Sahara Áfríkà yóò kópa tó lágbára nínú wíwá ojútùú sí ìṣòro àgbáyé. Ilẹ̀ náà yò di ibùgbé fún ìdá kan nínú mẹ́rin àwọn olùgbé ayé lọ́dún 2050 pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun àlùmọ́ọ́nì, èyí tí lára rẹ̀ jẹ́ igbó-òjò kejì tó tóbi jùlọ lágbàáyé àti ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún àwọn ohun àlùmọ́ọ́nì tó fún ayé yìí ní nǹkan àmúṣagbára. Pẹ̀lúpẹ̀lú, ó wà ní àwọn etí òkun tó ń ran ètò ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ àti kárà-kátà lọ́wọ́ lágbègbè Òkun Atlantic, Òkun Indian, àti Ọ̀gbun Aden. Agbègbè Afríkà yìí di ipò fìdí-hẹ mẹ́ta mú nínú Ìgbìmọ̀ Ètò Ààbò Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé, o sì ń ṣojú ọ̀kan nínú àwọn ẹgbẹ́ tó ń dìbò jùlọ (ìdá méjìdínlọ́gbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún) ní Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé àtàwọn lájọ-lájọ mì-ìn. Àwọn ọmọ Áfríkà wà ní ipò ńlá láwọn ẹ̀ka pàtàkì, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ Àjọ Ètò Ìlera Àgbáyé (WHO) àti Àjọ Okòòwò Àgbáyé (WTO).

Gbogbo àgbáyé ló mọ pàtàkì Áfríkà dénúdénú, èyi tó ń ṣe kóríyá fáwọn orílẹ̀-èdè káàkiri láti nawọ́ ètò òṣèlú, ọrọ̀-ajé, àti ètò ààbò fún àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè Áfríkà. Èyí mú àwọn àǹfààní àti ìpèníjà tuntun jáde lóri bí Áfríkà ṣe ṣe pàtàkì sí Amẹ́ríkà tó. Àwọn alábàáṣepọ̀ ní Yúróòpù, àárin-gbùngbùn Ìlà-Oòrùn (àwọn ẹ̀ya Arab), àti àwọn apá Òkun Indian pẹ̀lú Òkun Pacific kan (Indo-Pacific) ń fojoojúmọ́ mọ̀ pé Áfríkà kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú ọ̀rọ̀ ètò-ààbò wọn, ọ̀pọ̀ nínú wọn sì fara jìn sí ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Amẹ́ríkà láti mú ìgbéga bá ìdókòòwò tó ní òdiwọ̀n tó ga, tó jọ ojúlówó, tí kò sì ní màgòmágó nínú, àti láti dá sí wàhálà òṣèlú àti ètò ààbò. Ilẹ̀ China, nídàkejì, rí agbègbè yìí bíi agbo ìjà láti tàpá sí ìlànà ètò àgbáyé, láti mú àgbéga bá ẹ̀ka okòòwò àti òṣèlú agbègbè rẹ̀ tí kò gbòòrò tẹ́lẹ̀, láti tẹ́ḿbẹ́lú òótọ́-inú àti àkóyawọ́, àti láti sọ ìbáṣepọ̀ Amẹ́ríkà pẹ̀lú àwọn èèyan àti ìjọba Áfríkà di yẹpẹrẹ. Russia wo ilẹ̀ Áfríkà bíi agbègbè òmìníra fún ẹ̀ka àti iléeṣẹ́ jagunjagun aládàáni, èyí tó ń dá rògbòdìyàn sílẹ̀ kí wọ́n lè ní àǹfààní ìjẹgàba àti ọ̀nà láti pa owó. Russia ń lo ìbáṣepọ̀ nílànà ètò ààbò àti ọrọ̀-ajé, pẹ̀lú ìròyìn èké, láti tẹ́ḿbẹ́lú ìtakò Áfríkà sí bí wọn ṣe ń ṣàkọlù sí Ukraine àtàwọn ìwà títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn mọ́lẹ̀ níbẹ̀.

Amẹ́ríkà ń dá sí àwọn nǹkan táwọn orílẹ̀-èdè mí-ìn ń ṣe àti ipa tí wọ́n ń kó ní Ìhà Gúúsù Sahara Áfríkà, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń dá sí ọ̀rọ̀ agbègbè yìí tó ń la àyípadà ńlá kọjá lórí ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ, òṣèlú àti ààbò. Iye èèyàn tó wà ní Áfríkà ń pọ̀ sí i ju ti àwọn agbègbè àgbáyé tó kù, èyí tí yóò sọ agbègbè náà di èyí tó ní ìlú ìgbàlódé tó pọ̀ jù nígbà tọ́dún 2030 yóò ba fi dé. Agbègbè Áfríkà fún Òmìníra Kárà-kátà (The African Continental Free Trade Area), nígbà tó bá fẹsẹ̀ múlẹ̀ tán, yóò di agbègbè karùn-ún tí ọrọ̀-ajé rẹ̀ tóbi jù lágbàáyé pẹ̀lú agbára láti ní àpapọ̀ ọjà tó lé ní tríliọ́nù mẹ́ta

**AGBÈGBÈ NÁÀ NÍ ÒǸKÀ**

**ÀWỌN OLÙGBÉ:**

- Yóò ní ìdá mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún àwọn olùgbé àgbáyé lọdun 2050

**AGBÈGBÈ IBÙGBÉ:**

- Igbó-òjò kejì tó tóbi jù lágbàáyé
- Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún àwọn àlùmọ́ọ́nì tó ṣe kókó jù

**AGBÁRA:**

- Pẹ̀lú ìdá kan nínú ọgọ́rùn-ún, ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ tí wọ́n ń dìbò jù ní Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé

àti bílíọ̀nù irínwó dọ́là ($3.4 trillion). Agbègbè yìí ló ń darí ẹ̀ka ìdánilárayá, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ fíìmù, ẹ̀ṣọ́-ara, lítíréṣọ̀, àti orin, lọ́nà tí kò lẹ́gbẹ́.

Síbẹ̀síbẹ̀, àwọn ìdàgbàsókè dáadáa wọ̀nyí ti di yẹpẹrẹ nípasẹ̀ àpapọ̀ ogun àti ìfẹ̀míṣòfò; àyípadà ojú-ọjọ́; àìtó oúnjẹ; àti ìṣòro ìlera pẹ̀lú ọrọ̀-ajé tí àrùn COVID-19 dá sílẹ̀, èyí tó mú ìfàsẹ́yìn bá ìdàgbàsókè tó ti wà fún ogún ọ́dun, tó sì yọrí sí àìnílélórí àti ebi tí kò lẹ́gbẹ́. Ogun àti rògbòdìyàn tó ń wáyé ní Cameroon, Democratic Republic of the Congo, Ethiopia, Mozambique, Nigeria, Somalia àti ní tìbú-tòòró Sahel ká àwọn orílẹ̀-èdè Ìhà Gúúsù Sahara Afrika lọ́wọ́ kò láti gbárùkù ti àwọn nǹkan àjọṣe àgbáyé, bẹ́ẹ̀ ló tún nílo ètò owó fún oríṣìíríṣìí ìpẹ̀tùsáàwọ̀ àtàwọn ètò ọmọnìyàn. Bákan náà, àléébù tí wàhálà yìí dá sílẹ̀ ti di ilẹ̀ ọlọ́ràá fún àwọn afẹ̀míṣòfò láti gbòòrò sí i. Ikọ̀ afẹ̀míṣòfò ISIS áti al-Qaida ṣì wà ní àwọn orilẹ́-èdè Áfríkà púpọ̀, níbi tí wọ́n ti ń ṣe àkọlù tó ti fẹ̀mí ẹgbẹẹgbẹ̀rún èèyàn ṣòfò tó sì ń dúnkòokò mọ́ Amẹ́ríkà àti nǹkan tó yẹ fún ṣíṣe.

Bí Ìhà Gúúsù Sahara Áfríkà ṣe gbárùkù ti ìjọba àwarawa tó—ní òdiwọ̀n ìdá mọ́kàndínláàádọ́rin, gẹ́gẹ́ bí ìbò ṣe sọ láìpẹ́ yìí—ìjọba àwarawa kò wọ́pọ̀. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbàjọba ológun àti ìfàsẹ́yìn ìjọba àwarawa ti mú Áfríkà gírígírí láti ọdún díẹ̀ sí àsìkò yìí, èyí tó ṣeé ṣe kó mú ìfàsẹ́yìn bá ìṣèjọba àti ètò ààbò, bẹ́ẹ̀ ló lè ṣàkóbá fún àwọn orílẹ̀-èdè tó wà láyìíká. Lọ́dún 2022, àjọ Freedom House ṣàkọsílẹ̀ àwọn orilẹ́-èdè méjọ ní Ìhà Gúúsù Sahara Áfríkà gẹ́gẹ́ bíi olómìnira—èyí ni iye tó kéré jù láti ọdún 1991. Àwọn ìfàsẹ́yìn yìí ti fàayè sílẹ̀ sí i fún àtojúbọ̀ ilẹ̀ òkèèrè lọ́nà tí kò yẹ, ó sì fi bi àwọn ìjọba tó ń lo ìmọ̀-ẹ̀rọ láti tojúbọlé, fọ́n ìròyìn èké, hùwà jẹgúdú-jẹrá, fìyà jẹ ọmọnìyàn láì bìkítà, ṣe ń pọ̀ sí i hàn. Bí àwọn tó ń jà fún ìjọba àwarawa ṣe gbégbá orókè lásìkò ìdìbò ní Malawi àti Zambia láìpẹ́ yìí, bẹ́ẹ̀ làwọn tó ń ṣèjọba apàṣẹ-wàá láwọn ilẹ̀ mí-ìn di agbára mú káká. Àlàfo tó wà láàrin ìlàkàkà aráàlú àti ìdènà ẹ̀tọ́ láwọn orílẹ̀-èdè kan ti dá rúgúdù sílẹ̀ tí ìwọ́de sì ń wáyé.

★ ★ ★ ★ ★ ★

# ÀFOJÚSÙN ÀLÀKALẸ̀

Ilẹ̀ Amẹ́ríkà yóò lépa àfojúsùn mẹ́rin ní Ìhà Gúúsù Sahara Áfríkà—ọ̀kọ̀ọ̀kan yóò sì jẹ́ pẹ̀lú ìbáṣepọ̀ àwọn alábàáṣepọ̀ wa lágbègbè náà àti lágbàáyé, pẹ̀lú ẹlẹ́kajẹ̀ka nibi mejeeji. Àlàkalẹ̀ yìí rí àwọn àǹfààní dáadáa tó lágbára tó wà nínú àwọn nǹkan tí àwa àtàwọn alábàáṣepọ̀ ní Áfríkà jọ nífẹ̀ẹ́ sí. Bákan náà, a mọ̀ pé ní gbogbo ìgbà ni ọgbọ́n-àtinúdá Áfríkà yóò maa bá ìdènà pàdé pẹ̀lu bí ìjà gbẹ̀mí-gbẹ̀mí yóò ṣe máa da àwùjọ ẹ̀ rú, tí ìwà ìbàjẹ́ yóò máa fa ìlọsíwájú ọrọ̀-ajé sẹ́yìn, tí rúdurùdu yóò mu ohun àlùmọ́ọ̀nì ṣòfò, tí àìtó oúnjẹ yóò fẹrẹ di ìyàn àti àìríjẹtó fáwọn tó kù díẹ̀ káàtó fún, tí ìfàsẹ́yìn yóò sì ba gbogbo agbára ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àti òmìníra ìjọba àwarawa.

**Gbé Àkóyawọ̀ àti Àwujo ti o ni Àkóyawọ̀ lárugẹ**

Amẹ́ríkà nífẹ̀ẹ́ tó rinlẹ̀ fún òmìníra gbogbo èèyàn láti jàǹfààní agbègbè yìí, káwọn ìjọba àti aráàlú sì ní agbára láti yan ètò òṣèlú tí wọ́n fẹ́, èyí tó wà ní ìbámu pẹ̀lú ti àgbáyé. Àwùjọ tí òmìníra wà máa ń sáàbá ní àjọṣepọ̀ tó dán pẹ̀lú Amẹ́ríkà, bẹ́ẹ̀ ló ń fa kárà-kátà àti ìdókòòwò Amẹ́ríkà mọ́ra, ó tún ń lépa àwọn ètò tí yóò ran ìgbáyé-gbádùn aráàlú lọ́wọ́, ó sì ń gbógun ti àwọn ìwà China, Russia àtàwọn akẹgbẹ́ wọn tó ń hùwà ìpanilára.

- Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ìjọba ilẹ̀ Áfríkà, ẹgbẹ́ arannilọ́wọ́ (civil society), àti aráàlú láti mú ìtẹ̀síwájú bá òótọ́-inú àti ìjíyìn-iṣẹ́, èyí tí lára rẹ̀ jẹ́ àtìlẹ́yìn fún iṣẹ́ ìròyìn olùwádìí, ìgbógun tí ìjẹgàba àwọn tó mọ̀ nípa àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé (digital authoritarianism), ṣíṣètọ́jú òfin, àtúntò àtàwọn ìwà tó ń gbé ìjọba àwarawa lárugẹ. Pẹ̀lú ìgbaradì fún Àlàkalẹ̀ Amẹ́ríkà lórí Ìgbógun ti Ìwà Ìbàjẹ́, àkọ́kọ́ irú ẹ̀—pẹ̀lú ìgbọ̀wọ́ àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà—Amẹ́ríkà yóò lépa láti mú ìgbéga bá àkóyawọ̀ lórí owó tó wọlé fún ìjọba, yóò tú àṣírí ìwà ìbàjẹ́, yóó sì gbárùkù ti àtúntò.

- Amẹ́ríkà yóò tún tẹra mọ́ ìlékè-òfin, ìdájọ́ òdodo, àti iyì-ọmọnìyàn tó ń mú ìdìde-lẹ́yìn-ìṣubú rinlẹ̀ tó sì ń gbógun ti àtojúbọ̀. Ṣíṣe àtìlẹ́yìn fún òmìníra ẹ̀ka ètò ìdájọ́ jẹ́ àtakò ńlá fún ìfàsẹ́yìn ìjọba àwarawa, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ kíká àwọn adarí tó fẹ́ẹ́ kówó ìlú sápò lọ́wọ́ kò, tí wọ́n fẹ́ẹ́ yí òfin padà lọ́nà àìtọ́, tàbí ṣe màgòmágó ìbò. Ẹ̀ka ètò ìdajọ tó ní òmìníra yóò ṣètò ìpéjọpọ̀ àwọn aráàlú tó ń wá ìdájọ́ lórí ìwà ọ̀daràn, àríyànjiyàn, àtàwọn ìwà tó tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn mọ́lẹ̀.
- Amẹ́ríkà yóò ṣàtìlẹ́yìn fún àwọn orílẹ̀-èdè Áfríkà láti fi òótọ́-inú ṣàmúlò àwọn nǹkan àlùmọ́ọ́nì wọn, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ ohun àmúṣagbára àti àlùmọ́ọ́nì pàtàkì, fún ìdàgbàsókè alálòpẹ́, bẹ́ẹ̀ ni yóò tún ró ètò kárà-kátà lágbára lọ́pọ̀ yanturu, láì sí màgòmágó, àti lọ́nà tó ṣe é fọkàn tán. Síwájú sí i, Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ Áfríkà àti ẹlẹ́kajẹ̀ka láti wá ojútùú sí àìtó oúnjẹ kí wọ́n lè pèsè oúnjẹ lọ́pọ̀ yanturu láti kojú àìríjẹtó àti ìyàn tí Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé wòye pé ó ń bá ẹgbẹ̀rin mílíọ̀nù èèyàn fínra nílẹ̀ Áfríkà.

## Ṣàgbékalẹ̀ Àǹfààní Ètò Ìjọba Àwarawa àti Ààbò

Ìfọkansìn agbègbè yìí àti agbára láti gbé ìjọba àwarawa dìde, àti bí wọ́n ṣe lè fojú sùn, dá dúró, àti kí wọ́n kojú àwọn rògbòdìyàn tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń wáyé pẹ̀lu èyi tó ti pẹ́, yóò yọrí sáyọ̀ fáwọn èèyàn Áfríkà àti Amẹ́ríkà. Àjọṣepọ̀ tó lágbára wà láàrin ìjọba tó dá lórí iṣẹ́ àti èyí tó yẹra fáráàlú, ìwà ìbàjẹ́ tó gbilẹ̀, títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ ìfipábánilòpọ̀ àti ìfìyàjẹni, àti ètò ààbò tó mẹ́hẹ, èyi táwọn ikọ̀ afẹ̀mísọ̀fò àtàwọn ilẹ̀ òkèèrè tó hùwà láabi ń lò ní gbogbo ìgbà. Pẹ̀lú bó ṣe ń kojú àwọn ìwà yìí tó sì ń tẹnu mọ́ ọn pé ìjọba àwarawa ní àǹfààní púpọ̀, Amẹ́ríkà lè fún Áfríkà láwọn nǹkan tí wọ́n lè yàn bí wọ́n ṣe ń ṣèpinnu lórí ọjọ́ iwájú wọn, dín àyọnusí àwọn ọ̀bàyéjẹ́ nínú ìjọba àti ní ẹlẹ́kajẹ̀ka kù, àti láti dẹ́kun ìrànwọ́ tí yóò nílò ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó.

- Amẹ́ríkà yóò lépa láti dẹ́kun ìwà ìjẹgàba àti ìgbàjọba ológun pẹ̀lú ṣíṣe iṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ ní agbègbè yìí láti kojú ìfàsẹ́yìn ìjọba àwarawa àti títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ àpọ́nlé àti ìjẹniníyà. Bákan náà ni Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjọba mí-ìn àti ẹgbẹ́ ẹlẹ́kùnjẹkùn, bíi Àjọ Ìṣọ̀kàn Áfríkà (AU), láti kojú àìdùnnú aráàlú lórí bí àwọn ìjọba àwarawa kan kò ṣe wú wọn lórí, èyí tó ń fa àwíjàre àwọn tó ń fipá gbàjọba, àkójọpọ̀ àwọn tó ń lo àǹfààní rògbòdìyàn láti di gbajúmọ̀, àtàwọn tó jẹ gàba láti fòpin sí àǹfààní ìjọba àwarawa.
- Amẹ́ríkà yóò ṣàtìlẹ́yìn fún ìjọba àwarawa Áfríkà pẹ̀lú àtìlẹ́yìn fáwọn ẹgbẹ́ àrannilọ́wọ́ bíi ajàfẹ́tọ̀ọ́-ọmọnìyàn, ọ̀ṣìṣẹ́, àwọn adarí tó ṣàtìlẹ́yìn fún àtúntò; Amẹ́ríkà yóò ró àwọn ẹgbẹ́ táwọn èèyàn kọ̀ sílẹ̀ lágbára, bíi àwọn tí ìlànà ìbálòpọ̀ wọn yàtọ̀ (LGBTQI); yóò tún ṣàkójọpọ̀ àwọn obìnrin àti ọ̀dọ́ tí wọ́n ń lépa àtúntò; bẹ́ẹ̀ ni yóò gbárùkù ti ìdìbò tí kò ní màgòmágó nínú gẹ́gẹ́ bíi èròjà ìjọba àwarawa tó ṣe pàtàkì ṣùgbọ́n tí kò fẹsẹ̀ múlẹ̀ tó. Amẹ́ríkà yóò ṣàtìlẹ́yìn fún ìjọba àwarawa tuntun àtàwọn àǹfààní tó wà níbẹ̀ nípa mímú àgbéga bá àwọn ètò àti ìpàdé àpérò *Presidential Initiative for Democratic Renewal, the Summit for Democracy* ati *Year of Action*.
- Amẹ́ríkà yóò gbájú mọ́ ìgbìyànjú rẹ̀ lórí ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè mí-ìn, yóò lo àǹfààní àwọn ètò ìdàgbàsókè, yóò sì lo àwọn irinṣẹ́ ìdáàbòbò láti ró àwọn alábàáṣepọ̀ rẹ̀ lágbára kí wọ́n lè kojú àwọn tó ń dá rúgúdù sílẹ̀ lágbègbè yìí. A máa gbájú mọ́ mímú àgbéga bá agbára àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà láti mú ìgbé-ayé àti ètò ààbò dúró dééde nípa gbígba àwọn akọ̀ṣẹ́mọṣẹ́ elétò ààbò ìjọba tó ṣe é fọkàn tán lááyè láti ṣètò ààbò abẹ́nú. A máa náwó lórí ìgbìyànjú abẹ́lé láti kojú wàhálà àti láti gba àlááfìa lááyè, èyí tí yóò lo ìlàná *Global Fragility Act* ní apá Ìlà-Oòrùn Áfríkà tó wà létí òkun àti ní Mozambique.

- Amẹ́ríkà yóò gbájú mọ́ àwọn ohun èèlò tó ń gbógun ti ìfẹ̀mísọ̀fò láti dín ìdunkookò ẹgbẹ́ afẹ̀mísọ̀fò kùn lórí ilẹ̀ Amẹ́ríkà, sí àwọn èèyàn rẹ̀, sí àwọn ibùdó ìrànwọ́ àti ológun, àti láti kọjú ìjà nílànà òfin sí ibi tí ìdúnkookò yìí bá ti gbilẹ̀. A máa kọ́kọ́ ṣiṣẹ́ nípasẹ̀ àti pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ wa tó léwájú, pẹ̀lú gbogbo ìlànà tí a lè lò láti kojú ìfẹ̀mísọ̀fò ká lè gbógun ti ìwà yìí láì lo agbára jagunjagun bí kò ṣe ti aráàlú lásìkò tó yẹ. Lára ìlànà yìí ni lílo àwọn ètò tí yóò ró àwọn aláàbò abẹ́lé lágbára, ìwádìí, àti láti ran ẹ̀ka ètò ìdájọ́ lọ́wọ́ láti da àwọn afẹ̀mísọ̀fò, láti ká wọn lọ́wọ́ kò, àti láti ròyìn nípa wọn àtàwọn tó ń ṣàtìlẹ́yìn fún wọn.

## Mú Ìlọsíwájú Bá Ìlànà Bíbọ́ Lọ́wọ́ Àjàkálẹ̀ Àrùn àti Àǹfààní Ètò Ọrọ̀-Ajé

Ó ṣe pàtàkì láti sọ nípa ìṣòro méjì tó gbilẹ̀ jù lágbègbè yìí: àjàkálẹ̀ àrùn COVID-19 pẹ̀lú àtubọ̀tań ọrọ̀-ajé àti ètò àwùjọ tó mú wá. Àwọn ìpèníjà wọ̀nyí ti pọ̀ sí i pẹ̀lú ìṣòro kárà-kátà àti àìtó oúnjẹ tó wáyé nípasẹ̀ bí Russia ṣe ń kọlu Ukraine. Amẹ́ríkà fara jìn lórí àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjọba agbègbè àti alábàáṣepọ̀ lágbàáyé láti ṣètò ọrọ̀-ajé tó gbilẹ̀ fún Áfríkà. Àtìlẹ́yìn Amẹ́ríkà fún ìpadàbọ̀sípò agbègbè yìí jẹ́ ojúṣe pàtàkì lọ́na àti mú Áfríkà nígbàgbọ́ nínú ìdarí Amẹ́ríkà, mú àgbéga bá kárà-kátà àti ìdókòòwò Amẹ́ríkà, àti ìdásílẹ̀ iṣẹ́ fún Amẹ́ríkà àti Áfríkà.

- Amẹ́ríkà yóò gbájú mọ́ ìlànà àti ètò, bẹ́ẹ̀ ni yóò ró ìbáṣepọ̀ tó ti wà tẹ́lẹ̀ lágbára láti fòpin sí ipele àrùn COVID-19 tó burú àti láti ran ètò ìlera lọ́wọ́.
- Dídí àlàfo tó wà ní ọ̀nà tí Áfríkà fi ń múra de àjàkálẹ̀ àrùn àti bí wọ́n ṣe ń gbógun tì í ṣe pàtàkì sí Amẹ́ríkà àti ètò ìlera àgbáyé. Lóṣù keje, ọdún 2022, ìdá mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún àwọn èèyàn ilẹ̀ Áfríkà ló ti gba, ó kéré tán, ìpín àkọ́kọ́ abẹ́rẹ́ COVID-19, tí Amẹ́ríkà sì ń léwájú nínú àwọn tó pèsè abẹ́rẹ́ yìí pẹ̀lú ìwọ̀n igba mílíọ̀nù (200m doses) fún Áfríkà. A máa tẹ̀síwájú nínú ìpèsè ìwọ̀n yìí àtàwọn ìgbésẹ̀ tí yóò mú ìwúrí wá fún lílo abẹ́rẹ́ yìí, àti àtìlẹ́yìn fún ìgbésẹ̀ láti gbógun ti COVID-19 nílànà àyẹ̀wò, ìwádìí àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́.
- Amẹ́ríkà yóò ṣètò tó fẹsẹ̀ múlẹ̀ láti dènà, rí, àti láti gbé ìgbésẹ̀ lórí àjàkálẹ̀ àrùn asekúpani; láti dá sí ìpènìjà tó wà nínú ríra àti pípèsè abẹ́rẹ́ àjẹsára, àyẹ̀wò àti ìtọ́jú; láti ṣàtìlẹ́yìn fún ṣíṣe abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí àtàwọn oògùn mi-in; áti láti ró ìgbaradì àgbáyé lágbára lórí ìmúrasílẹ̀ fún irú àìlera yìí. Àjọṣepọ̀ ẹ̀ka ìjọba àti aládàáni pẹ̀lú ètò ìdarí lágbègbè yìí, nípasẹ̀ àjọ tó ń kojú àrùn ní Áfríkà (Africa Centres for Disease Control and Prevention) áti éyí tó ń ṣàkóso ètò ìlera ní Ìlà-Oòrùn Áfríkà (West African Health Organisation), fún àpẹẹrẹ, yóò jẹ́ igi lẹ́yin ọgbà fún ìrànlọ́wọ́ tí Ámẹ́ríkà yóò ṣe.
- Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú Áfríkà láti gbé ìdàgbàsókè lárugẹ àti láti ṣiṣẹ́ lórí gbèsè tó wà nílẹ̀ nípasẹ̀ àjọṣepọ̀ pẹ̀lú oríṣìíríṣìí ẹ̀ka, àlábàáṣepọ̀ àtàwọn ètò tó ti wà nílẹ̀ lágbàáyé láti mú ọrọ̀-ajé agbègbè yìí padà bọ̀ sípò. Nípasẹ̀ àjọ *Partnership for Global Infrastructure and Investment (PGII),* èyí tí *G7* (ẹgbẹ́ Canada, France, Germany, Italy, Japan, UK ati Amẹrika) pinnu láti ṣàkójọpọ̀ ẹgbẹ̀tá bílíọ̀nù dọ́là ($600b) fún, a óò lo àǹfààní yìí láti náwó, a óò sì ṣiṣẹ́ àkànṣe tí yóò mú ọrọ̀-ajé lágbára, tí yóò mú kárà-kátà gbòòrò, tí yóò sì mú àgbéga bá ètò ààbò Amẹ́ríkà àti Áfríkà. PGII yóò ṣètò tuntun tó dá lórí àgbéga àwùjọ, nǹkan àmúṣagbára àti ìpèsè oúnjẹ fún Áfríkà, ìyẹn *Prosper Africa, Power Africa, Feed the Future* àti ètò fún àyípadà àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé láti fòpin sí nǹkan amáyédẹrùn tí kò tó àti láti ṣàtìlẹ́yìn fún ètò ọrọ̀-aje tó rúgọ́gọ́.
- Amẹ́ríkà yóò tún ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè Áfríkà láti ṣe àgbédìde fáwọn òṣìṣẹ́ àti ìpèsè oúnjẹ, èyí tí àjàkálẹ̀ àrùn àti ogun tí Russia ń bá Ukraine jà mú ìfàsẹ́yìn bá. Amẹ́ríkà yóò ró akitiyan láti dènà òfò lágbára, yóò dènà kó bàjẹ́ ju bó ṣe wà, yóò sì dá sí ipò àìlágbára

tí owó tó wọlé fún ìdílé kọ̀ọ̀kan àti ìpèsè oúnjẹ wà, bẹ́ẹ̀ ni yóò ran àwọn ọmọdé lọ́wọ́—pàápàá àwọn ọmọdébìrin—láti padà síléèwé, àti láti ṣègbaradì fáwọn ọ̀dọ́ Áfríkà kí wọ́n lè fi ẹ̀bùn àti ìkọ́ṣẹ́mọṣẹ́ wọn kópa nínú ètò ọrọ̀-ajé sẹ́ńtíúrì kọkànlélógún.

**Gbárùkù ti Ìdáàbòbò, Ìfaradá Ojú-Ọjọ́, àti Ìṣípòpadá sí Nǹkan Àmúṣagbára tó Dáa fún Gbogbo Èèyàn**

Akitiyan Áfríkà láti dáàbò bo ètò ìbágbépọ̀ lágbègbè náà àtàwọn nǹkan àlùmọ́ọ́ńì—pẹ̀lú níní àǹfààní sí nǹkan àmúṣagbára àti ààbo tó péye fún un, mímú agbára yìí gbòòrò, àti ṣíṣe àgbékalẹ̀ ètò kárà-kátà alálòpẹ́—gbogbo èyí ni kókó ìgbìyànjú láti kojú wàhálà ojú-ọjọ́. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìgbéṣẹ̀ agbègbè yìí tó ń ba ojú-ọjọ́ jẹ́ kéré jọjọ, síbẹ̀, yóò jẹ nínú ìyà tí wàhálà yìí da sílẹ̀ lágbàáyé. Bí ìpè fún nǹkan àmúṣagbára ṣe ń pọ̀ sí i ní Áfríkà, a máa lo agbára wa, ìrànlọ́wọ́ ìdàgbàsókè, àti owó láti ran àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà lọ́wọ́ kí wọ́n lè kojú wàhálà tí àyípadà ojú-ọjọ́ ń fà kí wọ́n sì lè ṣe ìgbéláruge fáwọn ètò ọjọ́ iwájú láti dín kẹ́míkà tó ń ba afẹ́fẹ́ jẹ́ kù.

- Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjọba Áfríkà, ẹgbẹ́ arannilọ́wọ́ àtàwọn agbègbè abẹ́lé láti dáàbò bò, ṣàkóso àti láti sọ àwọn nǹkan àdáyébá tó ṣeyebíye dọ̀tun, èyí tó lè dín kẹ́míkà tó ń ba afẹ́fẹ́ àti wàhálà àyípadà ojú-ọjọ́ kù. A máa gbé ìgbésẹ̀ ńlá lórí ìgbìyànjú wa láti kọjú ìjà sáwọn to ń ṣe àwọn ẹranko inú igbó-ńlá báṣubàṣu tí kò sì sẹ́ni tó ń fẹjọ́ wọn sùn, àtàwọn tó ń pẹja lọ́nà àìtọ́. Amẹ́ríkà yóò ṣàtìlẹ́yìn fáwọn tó ń làkàkà kí ojú-ọjọ́ àti àyíká lè dáa, tí lára ẹ̀ jẹ́ ètò Amẹ́ríkà nípasẹ̀ *U.S. Plan to Conserve Global Forests: Critical Carbon Sinks* àti ti agbègbè ààrin-gbùngbùn Áfríkà nípasẹ̀ *Central Africa Regional Program for the Environment.*
- Amẹ́ríkà yóò súnmọ́ àwọn orílẹ̀-èdè pẹ́kí-pẹ́kí láti ṣiṣẹ́ lórí ìpinnu wọn tó dáa jù lórí nǹkan àmúṣagbára, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ rírí ààyè láti lo nǹkan àmúṣagbára lọ́nà ìrọ̀rùn àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé nípasẹ̀ ìmọ̀-ẹ̀rọ tí àpẹẹrẹ ẹ̀ jẹ́ nǹkan àmúṣagbára tó múná dóko àti èyí tó ṣe é sọ dọ̀tun, pẹ̀lú nǹkan amáyédẹrùn tó ń sọ gáàsì di nǹkan amáyédẹrùn. Iṣẹ́ yìí yóò máa lọ déédé pẹ̀lú àwọn ètò ńlá tá a ti ní lórí ojú-ọjọ́ àti nǹkan àmúṣagbára, bẹ́ẹ̀ ni yóò ṣàfihàn àtubọ̀tán ìdàgbàsókè àti àlàkalẹ̀ ètò àyíká lórí àwọn iṣẹ́ àkànṣe tá a ń ṣàtìlẹ́yìn fún. Amẹ́ríkà yóò ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè láti gbárùkù ti nǹkan àmúṣagbára tó dáa fún gbogbo èèyàn ni ìbámu pẹ̀lu ọrọ̀-ajé àti ètò ìbágbépọ̀ wọn. Ní ìparí, a máa ṣàkóso ìdókòòwò ẹ̀ka aládàáni Amẹ́ríkà àti Áfríkà láti ṣàtìlẹ́yìn fún àyípadà nǹkan àmúṣagbára, a óò ṣètò bí nǹkan àmúsagbára yóò fi gbòòrò sí i, bẹ́ẹ̀ ni a óò gbé ààbò àwọn nǹkan àmúsagbára láruge, pẹ̀lú ètò ojú-ọjọ́ àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé.
- Pẹ̀lú àtìlẹ́yìn ètò ìrànwọ́ *President's Emergency Plan for Adaptation and Resilience (PREPARE),* Amẹ́ríkà yóò túbọ̀ máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ìjọba Áfríkà tí ìjàm̀bá ojú-ọjọ́ kángun sí dáadáa ṣùgbọ́n tí wọn kò ní agbára púpọ̀ láti kojú ìjàm̀bá ọ̀hún kíákíá, ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìwádìí táwọn alábàáṣepọ̀ wa ti fi hàn wá.

Ní àkótán, Amẹ́ríkà yóò tẹ̀síwájú láti máa lépa ìbáṣepọ̀ ẹ̀ka ìjọba àti ti aládàáni láti mú àgbéga bá bí ààbò tó péye yóò ṣe wà fáwọn nǹkan àlùmọ̀ọ̀nì tí yóò ṣẹ̀dáa nǹkan àmúṣagbára ìgbàlódé, èyí tí yóò di lílò fún àyípadà nǹkan àmúṣagbára fún gbogbo àgbáyé. Amẹ́ríkà yóò ṣe kóríyá fáwọn orílẹ̀-èdè láti ṣètò àtúnṣe tí yóò mú ìdókòòwò alákòóyawọ́ tí gbogbo ayé tẹ́wọ́ gbà rinlẹ̀ láwọn agbègbè tó ní nǹkan àlùmọ̀ọ̀nì tó ṣe pàtàkì, bákan náà ni yóò tún mú ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lọ́kùn-ún-kúndùn, yóò sì máa hùwà ní ìbámu pẹ̀lú ààbò tí gbogbo àgbáyé ń fẹ́ fún àyíká àti eto ìbágbépọ̀.

**Ìwòye Ọgbọ̀n Ọdún Ètò Àmúlò tí Amẹ́ríkà Gbé Kalẹ̀**

Amẹ́ríkà ní ìtàn àti àtìlẹ́yìn ọlọ́jọ́-pípẹ́ tó mú ìwúrì wá pẹ̀lú Áfríkà, bó tilẹ̀ jẹ́ pé ètò àmúlò igun méjèèjì yàtọ̀, ṣùgbọ́n tí wọ́n gbé ìbáṣepọ̀ yìí lórí ìpìlẹ̀ àṣà tó jọra pẹ̀lú àfojúsùn àṣeyọrí kan náà. Láàrin ọgbọ̀n ọdún sí àsìkò yìí, ètò àmúlò Amẹ́ríkà, èyí tí Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin ṣàtìlẹ́yìn ńlá fún, mú ìdàgbàsókè lọ́kùn-ún-kúndùn, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ ètò ìlera aráàlù; kárà-kátà àti ìdókòòwò; ìjọba àwarawa àti ìṣèjọba; àti àlàáfíà pẹ̀lú ètò ààbò.
Ìbáṣepọ̀ yìí ti ran àwọn tó lé ní ogún mílíọ̀nù tó ní àrùn kògbóògùn *HIV/AIDS* lọ́wọ́, bẹ́ẹ̀ ló dènà àìsàn ibà tó fẹ́ẹ̀ kọlu àwọn tó lé ní bílíọ̀nù kan, ó fẹ̀yìn àìsàn *Ebola* janlẹ̀ ni Ìwọ̀-Oòrùn Áfríkà, ó sì pèsè iná mọ̀nàmọ́ná fún mílíọ̀nù mọ́kàndínlọ́gbọ̀n ilé àti iṣẹ́. Òfin *African Growth and Opportunity Act (AGOA),* èyí tí ilé ìgbìmọ̀ fọwọ́ sí lọ́dún 2000, mú àgbéga ńlá bá bí wọ́n ṣe ń ta àwọn ọjà Áfríkà kan sókè òkun, pàápàá aṣọ, èyí tó dá ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ iṣẹ́ sílẹ̀. Bí Amẹ́ríkà ṣe ṣàtìlẹ́yìn fún ìjọba àwarawa wà lára nǹkan tó jẹ́ kí ẹ̀tọ́ láti ṣe òṣèlú àti òmìnira aráàlú gbòòrò sí i láti ọdún 1990 di apá kan 2010. Amẹ́ríkà ṣàgbékalẹ̀ *Africa Command* lọ́dún 2007 láti gba gbogbo ọ̀nà kojú ìṣòro ètò ààbò ní Áfríkà àti láti náwó lórí ìpẹ̀tùsáàwọ̀ lágbègbè náà kí ojútùú ẹsẹ̀kẹsẹ̀ lè wà fún wàhálà tó bá ṣẹlẹ̀ lórí ààbò, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n tún fi àsìkò náà mú ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú agbègbè náà rinlẹ̀ sí i.
Amẹ́ríkà tẹ̀síwájú láti dá sí àwọn nǹkan pàtàkì títí di òní, ṣùgbọ́n púpọ̀ nínú àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ṣe nǹkan tẹ́lẹ̀ kò múná dóko mọ́ nítorí àwọn ìpèníjà tuntun tí ìfagagbága ń dá silẹ̀ lágbàáyé. Gẹ́gẹ́ bí Ààrẹ ṣe sọ, Amẹ́ríkà gbọ́dọ̀ fa gbòǹgbò ìwà ẹlẹ́yàmẹ̀yà tu ká sì fi kún ìgbìyànjú wa láti ní orílẹ̀-èdè tó bọ̀wọ̀ fún gbogbo ẹ̀yà. Àwọn orílẹ̀-èdè Áfríká tẹjú mọ́ ìlọsíwájú wa lórí èyí.
Pẹ̀lúpẹ̀lú, àwọn akitiyan tí Amẹ́ríkà fi ń gbé ìjọba àwarawa àti àlàáfíà láruge pẹ̀lú bí a ṣe ń lọ́wọ́ sí ètò ààbò kò ṣàṣeyọrí tó yẹ láàrin ọ́dun díẹ̀ sí àsìkò yìí. Àwọn àdarí Áfríkà kan ti ṣàtúnṣe sí òfin wọn láti fààyè gba àwọn àgbékalẹ̀ kan, wọ́n sì ń fi èyí pa àwọn kan lẹ́nu mọ́ pẹ̀lú bí wọ́n ṣe dojú kọ àwọn alátakò nídìí òṣèlú àti ẹgbẹ́ aranniléwọ́. Akitiyan Amẹ́ríkà láti kojú ìfẹ̀míṣòfò ti fòpin sí bi àtakò ṣe fẹ́ẹ̀ wáyé lórí àwọn ètò wa, bẹ́ẹ̀ ló ti dá ìgbésẹ̀ láti kọlu àwọn nǹkan tó jẹ wá lógún rú, a sì ti náwó nára lórí ìgbaradì ikọ̀ ológun àti ti aráàlú tó jẹ́ tàwọn alábàáṣepọ̀ wa tó ṣe kókó láti tẹrí ìdúnkòokò yìí ba, ṣùgbọ́n ìhàlẹ̀ àwọn afẹ̀míṣòfò àtàwọn alákatakítí ń pe àkíyèsí wa.
Nínú ìwòye àwọn àṣeyọrí wa tó làmìlaaka àtàwọn ìpèníjà wọ̀nyí, ìjọba Amẹ́ríkà ti fara jìn fún mímu ìgbà ọ̀tun bá àwọn irinṣẹ́ ìpìlẹ̀ ìjọba láti gbé àwọn ètò tó ní láruge káàkiri agbègbè Áfríkà tí àyípadà ń dé bá.

# ÀJỌṢEPỌ̀ ILẸ̀ AMẸ́RÍKÀ ÀTI ÁFRÍKÀ NÍ SẸ́ŃTÍÚRÌ KỌKÀNLÉLÓGÚN

Amẹ́ríkà gbọ́dọ̀ ṣàtúnṣe sí ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ojúgbà rẹ̀ ní Áfríkà, bẹ́ẹ̀ ló ní láti fetí sí àwọn ohùn ìbílẹ̀, kó sì mú àwọn nǹkan tó ń dá sí gbòòrò láti mú àgbéga bá ètò tó ní fún àǹfààní àwọn èèyàn Áfríkà àti Amẹ́ríkà.

- *Gbé Ìbáṣepọ̀ Amẹ́ríkà àti Áfríkà Sókè.* A máa ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà lórí àwọn nǹkan tí gbogbo àgbáyé mú lọ̀kùn-ún-kúndùn, pẹ̀lú àwọn nǹkan tó ń da ètò ààbò àti ìdàgbàsókè tiwọn náà láàmú. A máa sọ àwọn nǹkan tó jẹ wá lógún, a máa jíròrò lórí àgbékalẹ̀ wọn, a sì máa tọ́ka sí àwọn nǹkan tó ṣe pàtàkì sí àwa méjèèjì. A máa mú àfojúsun wa àti nǹkan tá a ń reti gbòòrò sí i lórí àwọn nǹkan tó tóbi tá a ń dá sí, bẹ́ẹ̀ lá o máa rí ìpàdé wa pẹ̀lú àwọn ojúgbà wa yìí bíi àǹfààní láti mú àgbéga bá nǹkan tí yóò ṣe àwa, agbègbè náà àti àgbáyé láǹfààní. Nígbà tí ìmọ̀ wa kò bá ṣọ̀kan, a máa ní sùúrù, a máa gbà láti tún pàdé, a sì máa jókòó láti wá ojútùú sáwọn nǹkan tó ń mú èrò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ wá.
- *Kó Àwọn Orílẹ̀-èdè Áfríkà Mọ́ra Sí i.* A máa mú àwọn nǹkan tá à ń dá s´i gbòòrò sí i, bẹ́ẹ̀ la máa náwó nára ní àwọn orílẹ̀-èdè ńlá bá a ṣé ń mú ìbáṣepọ̀ wà pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè tó tóbi díẹ̀ àtàwọn tó kéré jọjọ rinlẹ̀ láti mú àgbéga bá àwọn nǹkan tá a jọ nífẹ̀ẹ́ sí, èyí tí lára ẹ̀ jẹ́ àgbékalẹ̀ àyípadà ńlá fún Áfríkà, èyi tó ń jẹ́ *Agenda 2063*. Dídáàbò bo àwọn ìlànà ètò ààbò Amẹ́ríkà pè fún níní ìbáṣepọ̀ kan náà pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè ńlá àti kékeré. A máa ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn ilẹ̀ Áfríkà tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ìjọba àwarawa, fi kún ìrànlọ́wọ́ tá à ń ṣe, àti lílo àǹfààní tó bá wà láti ṣàtìlẹ́yìn fáwọn ìjọba tuntun wọ̀nyí tí wọ́n ní àfojúsùn dáadáa. A máa ṣakitiyan lórí àkójọpọ̀ àwọn alábàáṣepọ̀ wa tó làmìlaaka nípa níní ìbáṣepọ̀ tó gbòòrò sí i àti lílo àwọn abánijíròrò wa tó dáńgájíá ká lè lépa bí ètò àmúlò wa yóò ṣe bára mu nítorí àwọn nǹkan àmúyẹ tá a jọ ní, a óò sì ṣe èyí náà láwọn ìpàdé àpérò àgbáríjọpọ̀ àwọn orílẹ̀-èdè àti kóòtù àgbáyé.
- *Ṣàtìlẹ́yìn fún Ẹgbẹ́ Arannilọ́wọ́.* Ó ṣeé ṣe ká mú àgbéga bá àwọn ètò wa tí ẹgbẹ́ arannilọ́wọ́ agbègbè yìí, èyí tí lára wọn jẹ́ àwọn oníròyìn àti ajàfẹ́tọ̀ọ́-ọmọnìyàn, pẹ̀lú àwọn ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ àti ẹ̀ka ìjọba àwarawa, bá ṣàtìlẹ́yìn fáwọn nǹkan àmúyẹ ìjọba àwarawa tó pa wá pọ̀ bíi àkóyawọ́, ìjíyin iṣẹ́, oníruurú àmúyẹ, ètò dọ́gba-n-dọ́gba àti àìsí ìyànjẹ, ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin, àti gbígba àwọn èèyàn láàyè láti kópa. Nípa àrídájú pé ìrànlọ́wọ́ wà, bí a ṣe ń dá sí ètò àtàwọn ìkéde wa wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìmọ̀ràn ẹṣẹ̀kùkú, á máa túbọ̀ máa ṣàtìlẹ́yìn fún àwọn alátunṣe, àwọn tó gbárùkù ti ìjọba àwarawa, àwọn ẹ̀ka ètò ìlú, pẹ̀lú àwọn olórí ọ̀dọ́ àti obìnrin. Eléyìí tún ṣàkójọpọ̀ bí a ṣe wòye ìtàn àti ìṣẹ̀lẹ̀ àsopọ̀ tó wà láàrin sísọ nípa ìdájọ́ òdodo lórí ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ètò bí àwọn èèyàn ṣe lẹ́tọ̀ọ́ kan náà ni Ìhà Gúúsù Sahara Áfríkà àti Amẹ́ríkà.
- *Wòye Kọjá Ààlà Agbègbè.* A máa ṣètò àti àtìlẹ́yìn fún àkójọpọ̀ tuntun fáwọn tó wà lágbègbè kan náà, fẹsẹ̀ ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ẹlẹ́kajẹ̀ka múlẹ̀ sí i, nínú èyí tí Àjọ Ìṣọ̀kan Áfríkà àti ẹgbẹ́ tó ń rí sí ọrọ̀-ajé àwọn orílẹ̀-èdè Áfríkà (Regional Economic Communities) wà, a óò sì mú ìbáṣepọ̀ wa pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè àgbáyé gbòòrò sí i láti mú àgbéga bá àwọn nǹkan tá a jọ ń lépa. A máa ṣàkójọ àwọn orilẹ̀-èdè Áfríkà tí wọ́n ń ṣe àpérò lágbègbè Òkun Indian ati Indo-Pacific; a máa mú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè tó wà létí òkun ní Áfríkà, Yúróòpù pẹ̀lú àwọn ti Àríwá àti Gúúsù Amẹ́ríkà; bẹ́ẹ̀ la máa dá sí ètò ìjọba amúnisìn àtọwọ́dá tó ń dá ìyapa sílẹ̀ láàrin Àríwá Áfríkà àti Ìha Gúúsù Sahara Áfríkà. Pẹ̀lúpẹ̀lú, a máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ẹlẹ́kajẹ̀ka ní Áfríkà, Yúróòpù àti káàkiri láti ṣàgbéyẹ̀wò

ètò àgbékalẹ̀ agbègbè pẹ̀lú lílo àwọn àǹfààní tó wà láti ṣiṣẹ́ lóri àwọn ibi tí kò wúlò, àwọn nǹkan tó yẹ kó di ṣíṣe, àwọn nǹkan tó ṣe pàtàkì jùlọ àti bí ìnáwó lórí ètò yìí yóò ṣe wáyé.

- *Lílo Àwọn Èèyàn Áfríkà Tí Wọ́n Jẹ́ Ọmọ Amẹ́ríkà.* Àwọn èèyàn Áfríkà tí wọ́n wà lẹ́yin odi jẹ́ ìpilẹ̀ṣẹ̀ agbára. Nínú àwọn wọ̀nyi la ti rí àwọn ará Áfríkà tí wọ́n ti di ọmọ Amẹ́ríkà, àrọ́mọdọ́mọ àwọn tí wọ́n kó lẹ́rú tẹ́lẹ̀, àtàwọn bíi mílíọ̀nù méjì tí wọ́n ṣídìí kúrò ní Áfríkà ṣùgbọ́n tí wọ́n ṣì ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ẹbí, ètò àwùjọ àti ọrọ̀-ajé ilẹ̀ Áfríkà. Àwọn tó kúrò ní Áfríkà yìí wà lára àwọn tó kàwé tí wọ́n sì ṣoríire jù nílẹ̀ Amẹ́ríkà. Àjọ Ìṣọ̀kan Áfríkà ti rí àwọn èèyàn wọ̀nyí—ìyẹn àwọn ọmọbíbí Áfríkà tí wọ́n ń gbé láwọn ilẹ̀ mí-ìn—bíi agbègbè kẹfà (lẹ́yìn agbègbè Ìlà-Oòrùn, Ìwọ̀-Oòrùn, Gúúsù, Àríwá àti Àarin-gbùngbùn). A óò ṣàfikún ètò tá a ní fáwọn tó wà lẹ́yìn odi láti ró ìjíròrò láàrin àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba wa àtàwọn èèyàn Áfríkà tó wà lọ́dọ̀ wa lágbára sí i. A tún máa ṣàtìlẹ́yìn fún ètò Àjọ Ìṣọ̀kan Àgbáyé fáwọn ọmọbíbí Áfríkà, ìyẹn *UN's Permanent Forum for People of African Descent*. Nípaṣẹ̀ àwọn ìgbìyànjú wọ̀nyí, a máa lépa láti gbé ètò àmúlò Amẹ́ríkà lárugẹ, kojú ìròyìn èké, ró ìbáṣepọ̀ lágbára, bẹ́ẹ̀ la máa fẹsẹ̀ àsọyépọ̀ múlẹ̀.
- *Lo Àǹfààní Ẹ̀ka Aládàáni Amẹ́ríkà àti Ètò Ìdarí Abẹ́lé.* Ìjọba Amẹ́ríkà yóò fi kún ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ẹ̀ka aládàáni ilẹ̀ wa, bákan náà la máa ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn ìpínlẹ̀, ìlú ńlá àtàwọn àwùjọ kéékèèké láti ṣàfihàn bí ètò àmúlò Amẹ́ríkà fáwọn ilẹ̀ òkèèrè ṣe wúlò fàwọn tó wà nípele kejì àwùjọ (láàrin olówó àti aláìní). Ẹ̀ka aládàáni Amẹ́ríkà ń ṣiṣẹ́ pàtàkì lórí ìgbélárugẹ ìbáṣepọ̀ wa pẹ̀lú àwọn mì-ín àti àfojúsùn wa ní Áfríkà láwọn ẹ̀ka kan—bíi ètò ìlera, nǹkan amáyédẹrùn, ètò ìsúná, ètò ààbò, nǹkan àmúṣagbára tó dáa, ojú-ọjọ́, àti ètò ẹ̀kọ́. Àwọn ìpínlẹ̀ àti ìlù ńlá náà ń dá sí ètò àmúlò Amẹ́ríkà fáwọn ilẹ̀ òkèèrè. Lọ́dún 2017, ètò *City and County of San Fransisco Employees' Retirement System*, fún àpẹẹrẹ, fọwọ́ sí ìdókòòwò ọgọ́rùn-ún mílíọ̀nù dọ́là ($100m) fún iṣẹ́ àkànṣe nǹkan àmúṣagbára ní Áfríkà àtàwọn ọjà ìdókòòwò tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde. Láti sọ àpẹẹrẹ mí-ìn, ẹ̀ka ètò ààbò àti ìrànwọ́ Michigan, íyẹn *Michigan National Guard*, pèsè ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún iléèwòsàn àwọn ológun tó wà ní Liberia, lára ètò *State Partnership Program* rẹ̀. Ní àfíkun, a máa ṣètò bí àwọn adarí Áfríkà yóò ṣe máa rin ìrìn-àjò lọ sáwọn ibi tó kọjá New York ati Washington, lọ́nà àti gbé àṣà ìbílẹ̀ Amẹ́ríkà dìde fún ìgbélárugẹ kárà-kátà àti idòkòòwò, láti jí ìbáṣèpọ̀ àṣà dìde, àti láti wá àwọn alábàáṣepọ̀ mí-ìn tí yóò ran ètò wa lọ́wọ́.

★ ★ ★ ★ ★ ★

# ÌLÀNÀ TÍ A FẸ́Ẹ̀ LÒ

Àlàkalẹ̀ tuntun yìí yóò ta wá jí láti tún èrò pa, láti sọ dọ̀tun, àti láti ró àwọn ètò tó wà nílẹ̀ lágbára, bẹ́ẹ̀ ni ká lè ṣàgbékalẹ̀ ká sì ṣètò tuntun. Amẹ́ríkà yóò mú ọgbọ́n àtinúdá àti ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Áfríkà lọ́kùn-ún-kúndùn lọ́nà àti kojú àwọn ìpèníjà tó ń bá wa fínra lágbàáyé àti láti borí ìṣòro lágbègbè tuntun tí ìṣọ̀kan wà tó sì ní okun àti agbára yìí.

- *Ṣàtúnṣe sí Akitiyan Ìbáṣepọ̀ Pẹ̀lú Àwọn Orílẹ̀-èdè Mí-ìn.* A máa sọ àwọn irinṣẹ́ ìbáṣepọ̀ wa di ti ìgbàlódé, bẹ́ẹ̀ la máa ró àwọn aṣojú àti òṣìṣẹ́ wa nílẹ̀ òkèèrè lágbára láti ní ìjíròrò pẹ̀lu aráàlú ní Áfríkà, pàápàá àwọn ọ̀dọ́ àti obìnrin, nílànà tó rọrùn tó sì fi ọgbọ́n àtinúdá hàn. A tún máa ṣe kóríyá fún ìpàṣípààrọ̀ àṣà, bíi ayẹyẹ ìrántí ìkónilẹ́rún (*Year of Return)* tí wọ́n ń ṣe nilẹ̀ Ghana. Ní ìparí, a máa ṣakitiyan ńlá láti rí i dájú pé èèyàn àti owó wà láti ṣètò àti láti mú àwọn ayẹyẹ pàtàkì yìí wáyé.
- *Ṣàtìlẹ́yìn fún Ìdàgbàsókè Alálòpẹ́ àti Ìdìde-Lẹ́yìn-Ìṣubú.* Ìṣòro ńlá tó bá ètò ọrọ̀-ajé àti ètò òṣèlú àwùjọ nípaṣẹ̀ àrùn COVID-19 fi hàn pé a ní láti sọjí ká lè dín ewu kù ká sì mú àgbéga bá ìdìde-lẹ́yìn-ìṣubú nílùú àti lẹ́ka ètò. A máa mú iṣẹ́ wa pẹ̀lú ìjọba àtàwọn

agbègbè rinlẹ̀, àti pẹ̀lú Àjọ Ìṣọ̀kán Áfríkà, láti sàtìlẹ́yìn fáwọn tó ń mú ìdàgbàsókè alálòpẹ́ 'yá': àyípadà àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé, pàápàá lẹ́ka iṣẹ́ àti ètò àkọsílẹ̀; nínáwó sí ẹ̀ka ìlera, nínú èyi tí ọ̀rọ̀ òṣìṣẹ́ àtàwọn nǹkan amáyédẹrùn wà; mímú àgbéga bá ètò kárà-kátà fáwọn ọjà tó ṣe pàtàkì; rírí iná mọ̀nàmọ́ná lò; àti ìpèsè iṣẹ́ gidi. Amẹ́ríkà ló ń pèsè ètò ìdàgbàsókè tó pọ̀jù fún Áfríkà, a óò sì tẹ̀síwájú láti máa ṣèdásílẹ̀ àwọn ìlànà tó fẹsẹ̀ múlẹ̀, a óò máa wú àwọn iléeṣẹ́ Amẹ́ríkà lórí láti fi kún ètò ìdókòòwò àti ìbáṣepọ̀ wọn, a óò sì máa lo àwọn irinṣẹ́ àwọn ẹ̀ka àti àjọ tí kò sí lára awọ̀n tó ń ṣiṣẹ́ 'ìdàgbàsókè' tẹ́lẹ̀. A máa gbárùkù ti ètò ìdàgbàsókè tó bá àyíká mu, gbé ìpèsè oúnjẹ lọ́pọ̀ yanturu lárugẹ, ṣàgbékalẹ̀ ètò ìbágbépọ̀ tó bọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́ takọ-tabo tó sì mú àdínkù bá ìrẹjẹ àti rògbòdìyàn, bẹ́ẹ̀ la máa ṣe ojúṣe wa lórí owó tó ń wọlé fún ìjọba. Ní ìparí, a máa tẹ̀síwájú láti ṣe ojúṣe adarí fáwọn onígbọ̀wọ́ ètò ọmọnìyàn àti ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé.

- *Ṣàtúnrọ, Tún Owó Ná Sórí Àwọn Nǹkan Ìdáàbòbò Amẹ́ríkà.* Ikọ̀ ológun tó múnádóko, tó bá òfin mu, tó sì ṣe é jẹ́rìí àtàwọn ikọ̀ ètò ààbò mí-ìn ṣe pàtàkì sí àwùjọ tó kó àkóyawọ́, tó ní ìjọba àwarawa, tó lè dìde lẹ́yin ìṣubú, tó sì lè kojú ewu wàhálà láwọn ibòmí-ìn àti ní Áfríkà. A máa ṣàgbéyẹ̀wò àwọn irinṣẹ́ tá a fi ń bá àwọn ikọ̀ ológun ní Áfríkà lò, a óò sì náwó lórí wọn, pàápàá àwọn ètò tó ń ṣàtìlẹ́yìn fún ìrónilágbára láàrin ẹ̀ka tọ́rọ̀ kàn, a óò gbógun ti ìwà ìbàjẹ́, a óò sì ṣàtúnto ẹ̀ka ètò ààbò. A máa bẹnu àtẹ̀ lu títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn mọ́lẹ̀ àti ìfipá-gbàjọba látọ̀dọ̀ àwọn ikọ̀ aláàbò, pẹ̀lú ìwà lílo àwọn ọmọdé fún iṣẹ́ jagunjagun, bẹ́ẹ̀ la máa fi èyí sínú ìjóròrò ètò ààbò wa pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa níkọ̀ọ̀kan àti lápapọ̀. A máa tẹ̀síwájú láti ran àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà lọ́wọ́ lórí agbára tí wọ́n ní láti gbárùkù ti àláafíà àti ètò ààbò agbègbè wọn; láti kojú ìfẹ̀mísọ̀fò àtàwọn ìwà jàgídíjàgan mí-ìn; sa ipá tiwa lórí ètò ìdókòòwò orí omi tí Áfríkà ń ṣagbátẹrù; a sì máa pèsè ààbò tó yẹ fún ìjọba àwarawa àti àwùjọ tó ní ìlọsíwájú. Ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ètò ààbò ọdún 2022 (2022 National Defense Strategy), ẹ̀ka ètò ààbò wa yóò ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà láti tú àṣírí àti láti mọ̀ ní pàtó áwọn ewu táwọn ètò China àti Russia ni Áfríkà ń dá sílẹ̀. A máa ṣàmúlò ètò ààbò abẹ́lé tí ẹ̀ka aráàlú tí kì í ṣe ológun ṣètò fúnra wọn, bẹ́ẹ̀ la máa mú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ lórí ààbò pẹ̀lú àwọn tó ń ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú wa tí wọ́n sì ń fẹ́ àláafíà àti ìdúróṣinṣin múlẹ̀ sí i. A máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa lórí ètò ààbò ńi Áfríkà láti mọ ipa tí ewu ojú-ọjọ́ ń kó, a máa ṣètò tí yóò tètè tú àṣírí ewu yìí, a sì máa mú ìgbéga bá bí wọn yóò ṣe dìde lẹ́yin irú ìṣubú báyìí. Ní àfikún, a máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ẹ̀ka ààbò aládàáni tilẹ̀ Amẹ́ríkà nípasẹ̀ ètò *Prosper Africa* láti ṣàtìlẹ́yìn fún wíwá ojútùú sí ìmọ̀-ẹ̀rọ àti nǹkan àmúṣagbára táwọn ikọ́ ológun Áfríkà ń lò.
- *Ró Ìbáṣepọ̀ Kárà-kátà àti Okòòwò Lágbára.* A máa ṣàfikún sáwọn ètò àmúlò tó ti wà nílẹ̀ láti mú àgbéga bá ìdókòòwò àti kárà-káta Amẹ́ríkà ní Áfríkà. Nípasẹ̀ ìlànà àwọn ètò tí Ààrẹ wa ṣe, ìyẹn bíi *Power Africa, Prosper Africa, PGII* àti àgbéga àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé, a máa gbájú mọ́ àwọn ẹ̀ka tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ lórí àwọn àfojúsùn wa tí wọ́n sì ń pèsè nǹkan táwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà nílò, bíi ìṣòwò erè oko, nǹkan àmúṣagbára, ìdánilárayá, ìlera, àti ìmọ̀-ẹ̀rọ, lásìkò tá a bá ń mú ìdúnàádúrà wáyé láwọn ẹ̀ka tó ṣe pàtàkì sí ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé Áfríkà. A máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa ní Áfríkà láti ṣètò kárà-kátà àti ìrìn-àjò lọ́nà tó bá òfin mu, lásìkò tá à ń jọ ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ìròyìn tá a ní lọ́wọ́ láti dáàbò bo àwọn ibodè káàkiri Áfríkà. A máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn alábàáṣepọ̀ wa tó nífẹ̀ẹ́ láti mú ìbáṣepọ̀ kárà-kátà rinlẹ̀ kó sì gbòòrò sí i nípasẹ̀ àjọṣọ láti làlùyọ tó kó gbogbo wa mọ́ra. A máa mú àgbéga bá ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin ikọ̀ aṣọ́bodè àtàwọn oníṣòwò, ṣàfikún sí àmúlò ààbò fáwọn ọjà tó ń lọ káàkiri gẹ́gẹ́ bíi ìlànà ìjọba Amẹ́ríkà, bẹ́ẹ̀ la máa mú ètò fífi àkọsílẹ̀ wa han ara wa gbòòrò sí i. A máa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ilé ìgbìmọ̀ wa

lórí ọjọ́ iwájú òfin AGOA (African Growth and Opportunity Act), èyí tí yóò dópin lọ́dún 2025, a sì máa ṣàtìlẹ́yìn fún àmúlò ètò AfCFTA (African Continental Free Trade Area).

- *Ṣagbátẹrù Àyípadà fún Àkọsílẹ̀ Nílànà Ìgbàlódé.* A máa ṣètò àgbáríjọpọ̀ àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé tí kò ní àṣírí, tó ṣe é fọkàn tán, tó ṣe é lò pẹ̀lú àwọn nǹkan mí-ìn, pẹ̀lú ètò ayélujára, ìròyìn àti ìbánisọ̀rọ̀ nípa lílo ìmọ̀-ẹ̀rọ káàkiri Ìha Gúúsù Sahara Áfríkà. Àwọn iléeṣẹ́ ńlá àtàwọn tuntun nílẹ̀ Amẹ́ríkà nígbàgbọ̀ nínú àwọn àǹfààní tó wà ní Áfríkà, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń ṣe okùn ìbánisọ̀rọ̀ tó gba inú òkun kọjá, wọ́n ń kọ́ ibùdó àkọsílè nílànà ìgbàlódé sí i, wọ́n sì ń náwó lórí àwọn okòòwò tó ń gòkè àgbà ní Áfríkà. A máa ṣiṣẹ́ lórí àǹfààní láti lo ẹ̀ka ayélujára tí kò wọ́n, mímú àkọsílẹ̀ ìgbàlódé pọ̀ sí i láì náwó púpọ̀, bẹ́ẹ̀ là ń pè fún ìmọ̀-ẹ̀rọ ìgbàlódé tó wà fún gbogbo èèyàn bíi *Open RAN* láti mú àgbéga bá ètò ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ àti ìfipamọ́ àkọsílẹ̀ sínú afẹ́fẹ́ nílànà ìgbàlódé lọ́nà tówó ẹ̀ kò gara. A máa mú ìjọba àwarawa tuntun gbòòrò sí i, a máa kọjú ìjà sí ìjẹgàba lórí àkọsílẹ̀ nílànà ìgbàlódé, kojú ìròyìn èké, gbógun ti èébú tako-tabo lórí ayélujára, bẹ́ẹ̀ la máa ṣàgbékalẹ̀ ìlànà ìbọ̀wọ̀fúnni lóri ayélujára. Ní ìparí, lára bí a ṣe fẹ́ẹ̀ rí i dájú pé àwọn ọ̀dọ́ Afríkà ní àwọn nǹkan àmúyẹ àti ìmọ̀ tó gbòòrò, ẹ̀ka *Department of State* ati *United States Agency for International Development* yóò lépa láti lo àwọn ilé-ẹ̀kọ́ àti ẹ̀ka aládàáni wa láti ṣètò bí ẹ̀kọ́ oníwèé-ẹ̀rí láti orí ayélujára yóò ṣe wà fún ìmọ̀ sáyẹ́nsì, ìmọ̀-ẹ̀rọ àti ìṣirò.
- *Ṣíṣètò Ìdúródeede fáwọn Ibùdó Iṣẹ́ Ìgbàlódé.* Ní ìbámu pẹ̀lú ìfarajìn Ààrẹ Biden láti náwó lórí ìsọdọ̀tun àti ìpèsè nǹkan amáyédẹrùn nílé, Amẹ́ríkà yóò ran àfojúsùn àwọn ìlù ńlá Áfríkà lọ́wọ́ láwọn ẹ̀ka bíi nǹkan àmúṣagbára fún gbogbo èèyàn, ojú-ọjọ́ tó ń yí padà, ìfarada àyípadà àyíká, ìgbòkègbodò ọkọ̀, àti ìṣàkóso eto omi mímu àti kólẹ̀-kódọ̀tí. A máa ṣàfihàn ìfarajìn tuntun lórí ètò ìrónilágbára ní ẹsẹ̀kùkú àti ìgbéláruge àwọn irinṣẹ́ tí yóò mú àwọn nǹkan ìgbàlódé búyọ lọ́nà tí kò mú ewu dání tó sì mú Áfríkà dúró digbí lójú ìṣòro. Lílo ìlànà ìnáwó *Millenium Challenge Corporation (MCC)*, àwọn àjọṣepọ̀ wọ̀nyí yóò ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú àwọn ìjọba ẹsẹ̀kùkú; yóò ṣe àgbéyẹ̀wò tí yóò fi àwọn ìṣòro hàn àti nǹkan tó ń dá wọn sílẹ̀; yóò sì sàgbékalẹ̀ ètò tí yóò máa wo bí ìṣàkóso ẹsẹ̀kùkú ṣe ń gòkè àgbà ní gbogbo ìgbà. Ètò *MCC* pẹ̀lú ìlú ilẹ̀ Áfríkà kan ń bọ̀ lọ́nà tí yóò fìdí àgbékalẹ̀ tó dáńgájíá múlẹ̀, tí yóò kéde iṣẹ́ àti ojúṣe ẹnìkọ̀ọ̀kan, tí yóò sì ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Ilé Ìgbìmọ̀ láti dá sí àwọn ìṣòro tó ń kojú òfin ṣíṣe.

★ ★ ★ ★ ★ ★

# ÌPARÍ

Nínú ọ̀rọ̀ àpilẹ̀kọ rẹ̀ fún Àjọ Ìṣọ̀kan Áfríkà lóṣù kejì, ọdún 2021, Ààrẹ Biden tún kéde bí ayé tí à ń gbé ṣe so mọ́ra tó—àti bí ìgbé-ayé wa ṣe so pọ̀. Àláàfíà Àfrìkà àti oríire rẹ̀ jẹ́ nǹkan pàtàkì tí yóò ṣàtìlẹ́yìn fún agbára Áfríkà láti wá ojútùú sí ìṣòro àgbáyé. A mọ̀ pé àfojúsùn wa bára mu, ọ̀nà àṣeyọrí wa sì dúró lórí ìfarajìn láti ṣiṣẹ́ papọ̀ ká sì gbé ìdarí Áfríkà sókè fún ètò àjọṣe. Ààrẹ Biden wòye pé “kò sí nǹkan kan tí yóò rọrùn nínú èyí” ṣùgbọ́n ó fi ìgboyà sọ pé “kò sí àní-àní pé àwọn orílẹ̀-èdè wa, àwọn èèyàn wa, Àjọ Ìṣọ̀kan Áfríkà – a kúnjú òṣùwọ̀n.”

**OFIISI AARE**
**AJO ELETO AABO**
**WASHINGTON, DC 20503**